# IJỌ, IYAWO KRISTI

## Efesu 5:1-33

## ẸKỌ 403 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ má si ba aileso iṣẹ òkunkun kẹgbẹ pọ̀, ṣugbọn ẹ kuku mã ba wọn wi" (Efesu 5:11).**

### Iwe Paulu

Jesu kò jẹ sọ ọrọ kan ti kò ni ṣe anfaani, bakan naa ni ọrọ awọn Apọsteli Rẹ̀ ṣe anfaani ti o si jẹ́ otitọ. Nigba ti Paulu Apọsteli ba waasu fun awọn eniyan, tabi ti o ba kọ iwe ranṣẹ si wọn, iṣẹ ti o n ran si wọn lagbara pupọ.

Lati Romu, Paulu kọ iwe si ijọ ti o wà ni Efesu pe ki wọn ki o "rin ni ifẹ." Bakan naa ni a ran iṣẹ yii si awa lonii pẹlu. O kọwe yii ranṣẹ gẹgẹ bi baba oninuure ti o n rọ̀ wa pe ki a tẹle Ọlọrun gẹgẹ bi "ọmọ ọ̀wọ́n." Nipa ẹ̀da, gẹgẹ bi awọn ọmọde ti n jọ awọn obi ti o bi wọn, bakan naa ni igbesi ayé ọmọ Ọlọrun ṣe ni lati ni aworan Kristi ki o si maa so eso Onigbagbọ. Mimọ́ ni Ihinrere Jesu Kristi, o funfun lau, o si pe. Ọrọ were ati iṣẹfẹ "ko tọ́", ko si yẹ ni igbesi aye awọn Onigbagbọ. Jesu wi pe, "gbogbo ọ̀rọ wère ti enia nsọ, nwọn o jihin rẹ̀ li ọjọ idajọ" (Matteu 12:36). Ọrọ were ko nilaari, ko si lere, awọn ọ̀rọ ti ko niyelori. Ninu isọwọ kan naa ni iṣẹ̀fẹ ati ọ̀rọ wère ti o ni itumọ ibi tabi ti o kún fun eeri wà. Ko si àye fun eyi ninu ọ̀rọ awọn Onigbagbọ. A kà ninu iwe Oniwaasu 10:1 pe "wère diẹ" ninu ẹni ti a rò pe o jẹ ọlọgbọ́n ti o si lọlá dabi okú eṣinṣin ninu ororo ikunra. A sọ fun wa pe ki a má rin gẹgẹ bi "awọn alailọgbọn, ṣugbọn bi awọn ọlọgbọn."

"Ẹ mã rin gẹgẹ bi awọn ọmọ imọlẹ." Ẹṣẹ ni òkunkun, Eṣu si ni ọmọ alade okunkun. A kilọ fun wa pe ki a má ṣe ba ẹlẹṣẹ kẹgbẹ pọ, ṣugbọn ki a kuku maa ba wọn wi. Awọn ta ni ọrẹ rẹ? Awọn ta ni iwọ n ba kẹgbẹ -- Onigbagbọ tabi awọn ẹlẹṣẹ? Nigba pupọ igbesi aye mimọ́ awọn Onigbagbọ a maa jẹ ibawi fun awọn ẹlẹṣẹ, bi o tilẹ jẹ pe a ko sọ ẹyọ ọrọ kan. Ṣugbọn nigba ti Oluwa ba ṣi ọna, ẹ má ṣe jẹ ki a fa sẹyin lati sọ ẹyọ ọrọ kan fun Jesu. Máṣe fi imọlẹ rẹ pamọ "sabẹ òṣuwọn."

### Ọjọ Ibi

Ẹsẹ 14 dabi iro ipe, "Ji," "Jinde". Ki ni ṣe ti iṣẹ naa fi jẹ́ kanjukanju? "Buburu li awọn ọjọ." Wá iṣẹ fun iṣẹju kọọkan! Ko si ifi akoko ṣofo; kukuru ni akoko! "Ẹ má si ṣe mu waini li amupara." ṣibẹ awọn ọna miiran wà ti a fi le mu "amupara" ki a si sọ Ẹmi Ọlọrun nù. Awọn miiran wà ti afẹ́ ati aniyan ayé yii fẹrẹ maa "pa bi ọti." Kika iwe asiko gba awọn ọdọmọde miiran lọkàn kan to bẹẹ gẹẹ ti wọn fi n huwa bi ẹni ti o mu "amupara", wiwo ẹrọ amohun maworan ijo ti ko awọn ẹlomiran lẹru to bẹẹ ti o ti di "amupara" fun wọn; ile ijo ti kó awọn ẹlomiran lẹru to bẹẹ ti wọn ko le ṣe ki wọn má lọ; bẹẹ gẹgẹ ni aṣa igbalode kó awọn ọmọbinrin miiran lẹru to bẹẹ ti aṣa aye yii fi gba gbogbo ero ọkàn wọn. Ṣugbọn eyi kò ri bẹẹ pẹlu awọn Onigbagbọ.

Awọn wọnni ti n fasẹyin kuro lọdọ Ọlọrun le wi pe: "Kò ṣe nnkankan, ọmọde sa ni mi! Mo si ni lati gbadun ayé mi. Ki lo buru ninu wiwo aworan ti n rin (cinema) lẹẹkọọkan? Ki ni buru ni wiwo ẹrọ amohùn-maworan (television)? Njẹ o le pa mi lara bi mo ba mu ẹyọ sigá kan?"

Ni ilu okere rére nigba ti awọn ọdọmọdekunrin jagunjagun ba da nikan wà jinna sile, awọn ọmọdekunrin miiran a maa wi bayii pe: "Ki ni buru ni wiwo aworan ọfẹ ti o n rin (cinema)? Ko ju pe ki n joko pẹlu awọn ọmọ miiran ninu papa ti o gbooro ti o si tẹju. Ki ni ohun ti o buru ninu eyi? O buru nitori pe bi o ba lọ lẹẹkan, iwọ yoo ni ifẹ ati maa lọ lati igba de igba. Bi o tilẹ jẹ pe ọpọ eniyan ni o sọ pe kò le pa ni lara sibẹ yoo sún ọ lati ṣe ohun ti o buru ju eyi ni lọ. A maa n gbọ́ ẹri awọn ẹlomiran pe ṣaaju ki wọn to ri igbala, pe o tẹ wọn lọrun lati lọ wo aworan ti n rin ju ati jẹun lọ. Ọdọmọdekunrin kan jẹri bayii pe, "Emi kò ri itẹlọrun ninu wiwo aworan ti n rin; igba gbogbo ni mo n ni ijatilẹ." Ẹlomiran wi bayii pẹlu wi pe, ohun gbogbo ti o wà ni ayika ni o di okunkun ni ọjọ kin-in-ni ti oun fi ẹsẹ tẹ inu ile ijo. Ọpọlọpọ aworan ti wọn fi han ni ko ba oju mu ti wọn si le ba ọkàn eniyan jẹ.

Eredi rẹ̀ ti Onigbagbọ ko fi ni lati gbe ẹrọ amohùn-maworan (television) si ile wọn ni pe ọkàn agbalagba ati ọmọde a maa fa si wiwo o to bẹẹ ti ko fi ni si àye mọ fun awọn ohun ti o ṣe pataki. Inu ile meloo ti o ni ẹrọ amohùn-maworan ni o ti le ri pẹpẹ adura? Ẹrọ amohùn-maworan ko le ri àye ninu igbesi aye ọmọ Ọlọrun nitori pe ọpọ ohun ti a n fihan ninu rẹ̀ ni o n fi iwa buburu ati ibajẹ hàn. Awọn miiran tilẹ le wi pe, wọn a maa fi aworan ti o bojumu han nigba miiran, ṣugbọn alufaa Ọlọrun kan sọ bayii nigba kan pe "Onjẹ daadaa a maa wà ninu panu idalẹnu nigba miiran, ṣugbọn njẹ iwọ le rán ọmọ rẹ lọ sibẹ lati lọ jẹ ẹ"?

"Ẹ mã tẹriba fun ara nyin." Ẹni meloo ni o n fẹ tẹriba! Boya wọn tilẹ wa ni ipo àre – gbogbo eniyan ni o n jare loju ara rẹ̀ ni gbogbo igba – ṣugbọn Oluwa yoo bukun fun wa ti a ba le tẹriba, bi o tilẹ jẹ pe a ro pe a wà lori àre. Ninu 1 Peteru 5:5, a kà bayii pe, "Ẹnyin ipẹ̃rẹ, ẹ tẹriba fun awọn àgba." Imọran ni eyi fun awọn ọmọkunrin ati ọdọmọdebinrin pe ki wọn ki o tẹriba fun awọn obi, olukọ ati awọn alufaa wọn.

**Iyawo Kristi Mimọ́**

Ẹsẹ 20-33 jẹ eyi ti awọn alufaa n kà nigba pupọ nibi isin igbeyawo nitori ti wọn fun ni ni aworan irẹpọ timọtimọ ti o wà laaarin ọkọ ati aya.

Isọkan kan wà ti igbeyawo n mu wá nigba ti ọdọmọkunrin kan ati ọdọmọbinrin kan ba fi baba ati iya wọn ati ile wọn silẹ lati wà pọ titi ikú yoo fi ya wọn. (Gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun ikọsilẹ ati atungbe iyawo ki i ṣe ilana Ọlọrun bi o tilẹ jẹ pe ofin ilẹ wa fi aayè gbà á).

Aworan miiran ti o tun fi ara jọ eyi ti a le mu jade lati inu ẹkọ yii ni pe Jesu Kristi fi ookan aya Baba Rẹ̀ lọrun silẹ, Ó wá si ayé oṣi yii lati fẹ́ Iyawo, Ijọ Akọbi, fun ara Rẹ̀ lati inu ayé ti o ti sọnu. Lai pẹ Jesu yoo de lati wá mu Iyawo Rẹ̀ lọ si ibi Ase-alẹ Igbeyawo Ọdọ-agutan, ère ti o ga ju lọ ti Onigbagbọ le gbà. A ni lati sa gbogbo ipa wa ki a le ni ipin ninu ère ologo yii!

Awọn ijọ ẹlẹsin lode oni ti sùn, nigba ti Ọlọrun n pe awọn ti o ti ji ninu ẹmi, lati jẹ Iyawo fun Ọmọ Rẹ̀.

Igbeyawo alarinrin ki i dede wà lasan lai jẹ pe a ti ṣe ipalẹmọ ati imurasilẹ kinnikinni fun ohun gbogbo. Njẹ o ti lọ si ibi igbeyawo ri ki o si ṣakiyesi aṣọ iyawo bi o ti funfun ninnin lai si abawọn? O ko ri ẹrin musẹ ti o wà loju iyawo bi o ti fi ọwọ́ kọ́ ọwọ ọkọ rẹ̀? Gbogbo nnkan wọnyii kọ wa lẹkọọ nipa bi a ṣe ni lati mura lati pade Jesu ti o n bọ̀ wá mu awọn wọnni ti o mura silẹ lati pade rẹ̀. "Ẹ jẹ kì a yọ̀, ki inu wa ki o si dùn gidigidi, ki a si fi ogo fun u: nitoripe igbeyawo Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan" (Ifihan 19:7). Ẹ jẹ ki a ri daju pe ko si ohun kan ti gboju fo dá a gbọdọ ri igbala nipa Ẹjẹ Ọdọ-Agutan. A gbọdọ mu ohunkohun ti o wọ́ bọ̀ si titọ eyi ti a ti ṣe lati ṣẹ ẹlomiran. Iribọmi lẹyin ti a ti ri igbala jẹ pataki pẹlu. A ni lati sọ wa di mimọ́, nipa Ẹjẹ Jesu. Eyi jẹ iṣẹ oore-ọfẹ keji, nigba ti a ba fi Ẹjẹ Jesu wẹ ọkàn wa. Iriri yii a maa fun ni ni igbesi ayé mimọ́, ifẹ ti o jinlẹ fun Ọlọrun ati ẹlomiran. "Ki on ki o le mu u wá sọdọ ara rẹ̀ bi ijọ ti o li ogo li aini abawọn, tabi alẽbu kan, tabi irú nkan bawọnni; ṣugbọn ki o le jẹ mimọ́ ati laini àbuku" A kà ninu Heberu 12:14, pe, lai si iwa mimọ́ "ko si ẹniti yio ri Oluwa."

Lẹyin isọdimimọ a ni lati ṣafẹri a si ni lati ri Ẹmi Mimọ́ ati ina gbà. A fi iriri ologo yii wé "aniṣẹku" ororo, tabi Ẹmi Ọlọrun, eyi ti awọn wundia ọlọgbọ́n wọnni ti o jade lọ pade ọkọ iyawo ni. (Ka Matteu 25:1-13). Awọn wundia alaigbọn ti ko ni aniṣẹku ororo, tabi Ẹmi Ọlọrun, ni a tilẹkun mọ́ sode.

Lẹẹkan si Paulu mu ero wa pada si ile Onigbagbọ o si sọ ifẹ ti o wà laaarin ọkọ ati aya, isopọ ti o ga ti o sọ awọn mejeeji di ọ̀kan. A fi iru ifẹ yii wé ti Kristi ati ijọ, a si pe e ni "Aṣiri nla."

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni a sọ ninu ẹkọ yii nipa ọrọ wère ati ẹ̀fẹ?
2 Ki ni itumọ Ijọ ti ko ni abawọn tabi aleebu?
3 Bawo ni Ijọ tootọ ti sunmọ Kristi tó?
4 Bawo ni a ṣe mọ pe buburu ni awọn ọjọ?
5 Ki ni itumọ "rira igba pada"
6 Sọ orişirişi ọna ti awọn eniyan fi le di "alamupara."
7 Ki ni itumọ pe ki a tẹriba?
8 Ki ni itumọ "awọn ọmọ imọlẹ"?
9 Ta ni Ori Ijọ?
10 Bawo ni a ṣe le di mimọ́?